AKIYESI

Ẹ sare tete wa ra awọn ọja ti o ya nile wonyi:-
Cash and Rent Recipt 6s dozen, £3 15s gross, Calendar 1958, 4s 6d dozen, £2 8s gross, Gbedegbeyo Hausa £1 4s dozen, £12 8s gross, Goldsmith Receipt, complete set 17s 6d, ati orisirisi oja be.
nte Iwe fun Sosi, Ile-Iwe Egbe ati bebe, ao te kiakia, yio si te yin lorun. E kowe si:- Manager

*Iyeru Press and Bookshop 68 Clifford Street, Ebute-Metta*


# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.


SPACIOUS ROOM & VERANDAH

TO LET

*Top Floor :-*

16, Bamgbose St., LAGOS.

Phone 24318.

VOL. 1 No. 32, WEDNESDAY 5, FEBRUARY — FEBRUARY, 11, 1958 KỌBỌ KAN

# Won Pa Enia Ni Osan Gangan Ni Oja Oyingbo

**Emo, ipania ni osan gangan! Ko din ni** enia mejila ti o fi oju ri eleyi nigbati o sele ni oja Oyingbo ni Ebute metta, ni ojo Oyingbo ti o koja ni ojo Sunday.

Mallam Abdul Raimi ẹni ọdun marun-diladọta, ti o ngbe 52, Denton Street, ṣubu lulẹ o nluwẹ ninu ẹjẹ, bẹni o si ku. Bi ọkunrin kan ti mbẹ kiri ọjà bẹni awọn enia nsare le e ti nwon si kigbe "ole, ole, ole". Abbul Raimi na sare tẹle o si gba mu.

Awọn mejeji wọ iyaja pẹrẹwu fun igba diẹ, larin meji eyi, ọkunrin na yọ ọbẹ oloju meji o si gbaa mọ ni ọrun ni ẹgbẹ ọtun o si ba ẹgbẹ osi jade o si ja ni gogogongo.

Ọgbẹni Ogba Onuaha, ara Aba ti o wa sowo ni Eko rohin bi eyi ti ṣe ṣẹlẹ fun ọlọpa.

O ni on patẹ awọn aṣọ wiwọ "Bọ si corner" silẹ, on si ba awọn ti o wa nitori on sọrọ, bẹni ọkunrin kan si gbe aṣọ awọsoke awọn obinrin kan (blouse) oni ṣile mẹfa ti o si nsalọ. On si lọgun Ole, gbogbo ọja si gba le ọkunrin na.

Ọlọpa mu ọkunrin kan, Alabi Dangar Ima, ti o ngbe 5, Bọla Street fun ohun ti o ṣẹlẹ yi.

enia mẹsan ni ọlọpa da duro lati gbọ ti ẹnu nwọn. Ninu wọn ni Idowu Sanni ọrẹ Raimi Ima gbe wa.

Awọn mejọ yoku jẹ awọn onisowo ti o nta ọja nitosi ibiti jamba yi gbe ṣẹlẹ.

E o ma ka ninu iwe yi bi wọn ba ti ṣe ṣe ẹjọ na si, awọn ọlọpa si nṣe iwadi lọwọ.

# A Se Eye Fun Bassey Ni Ilu LIVERPOOL

Liverpool

AWỌN ENIA BI ỌGỌTA TI WỌN JẸ ISANGBE HOGAN "KING" BASSEY ṢE EYE SISE ASE FUN NI LIVERPOOL NI ALẸ ỌJỌ ẸTI (FRIDAY) TI O KỌJA.

Awọn isọngbe rẹ jẹ lara awọn ti wọn ti nba lọ si ibiti o ti nja ni gbogbo agbaiye wọn si so wipe Hogan Bassey jẹ enia jẹjẹ ati alakikanju ninu awọn elere, wọn si dide wọn tun kọrin bayi wipe "nitori ti o jẹ ẹni rere."

Ninu ọrọ ṣoki ti Bassey sọ, o so ọrọ iyin nipa awọn ti o ran ohun lọwọ, awọn bi Deejaysee, Harry Ormisher, isangbe rẹ kini ati John Moores, Ọgbẹni ti o ni owo pupọ. Ọgbẹni Harry Ormisher ti sọ asọtẹlẹ wipe Hogan Bassey yio jẹ ọgagun ninu ija rẹ ti yio ja ni Amẹrika.

A ni igbagbọ wipe ni igbati Ọgbẹni Hogan Bassey yio ba fi ẹṣẹ jija silẹ ko ni si eniti y i o ṣẹgun Ọgbẹni HARRY, Omisher ni o tun sọ eyi. Ọgbẹni Johnny Best ti Liverpool sọ wipe ihuwasi Bassey ninu ati lode ni ibi ija ti ṣe ohun ribiribi lati fihan wipe ko si iyato larin enia dudu ati funfun ninu ẹṣẹ jija.

Ṣugbọn a ro wipe ọrọ ti o jẹ eyiti o ni iyi julọ ni o wa lati ọdọ Ọgbẹni John Moores, olowo tabua ni, ti o sọ wipe Hogan jẹ enia ti oun le pe ni aburo tabi ọmọ oun.

Bassey jẹ ọga ni gbogbo agbaiye ninu ipo tirẹ, ninu awọn akanṣẹ nigbati o ṣẹgun Cherif Hamia ti ilu Faranse ni ọdun ti o kọja yio wa ba arakunrin kan ti a npe ni Richards Moreno ti ilu Mexico ni Wrigley-Field ni itosi Los Angeles ni ogunjọ oṣu kẹta ọdun yi.

Fun ija yi, yio gba owo to to £25,000 ati Ọgbẹni Moreno papa yio gba £13, 570.

Ṣugbọn a gbọ wipe Bassey yio ti lọ si ilu Amẹrika fun bi ọsẹ mẹta tẹlẹ ki wọn ta ja ija yi, a si ro bi ọga rẹ ọgbẹni George Biddles, Olukọ rẹ ọgbẹni Fox ati ọgbẹni Ormisher yio ba lọ pelu.

Ni ẹnu lọlọ yi Bassey ṣẹgun kan ni Liverpool. O ṣẹgun Pierre Cossemyns ti ilu Belgium nin ija wọn. Iṣẹgun rẹ yi han ketekete iati fi gbesan fun eyiti wọn ja ni ijọsi ti Cossemyns fi ṣẹgun Bassey ni ilu Leeds ni ọdun kẹfa sẹhin (1952).


# AWON OJA ODUN TITUN

Turari fun Arisiki lati ilẹ India 10/6d
Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan ati Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbeyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Turari Itaja 10/6d
Turari Ẹyọnu Ajẹ 10/6d
Abẹla Adura (Dragon Candle) fun Adura tete Dami lohun 15/-6d

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tab:
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

# IMỌLẸ

ESIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lagos**
**Telephone: 21985**

*London Office—*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. I.*

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN EKO—ṢILE MẸRIN KỌBỌ MẸRIN (4/4d)
Ilu ·iran ni Naijria ati Oke-okun Ṣile mẹfa Kọbọ mefa 6/6d)

## IMORAN FUN AWON ONI KEKE OLOGERE

Lọwọ iku ojiji Oluwa rere gba wa ma jẹ ki a rin ni ọjọ ti ebi yio pa ọna (amin). Ẹnyin ara imọran ti awa oniwe yi fẹ gba yin ti ẹ da le tẹle yio dara pupọ nitoripe ẹmi wa ko pe meji.

Lọna kini yio dara fun wa lọpọlopo ti a ba fẹ lo sibi iṣẹ tabi ode ki a ma tetẹ jade nile nitoripe ikanju pẹlu ifarabalẹ ọkan na ni, o fẹrẹ jẹ ikanju ati amọju lo ma nfa iku ojiji fun onikẹkẹ ologere nitori opolopo igba ni ẹlomiran ma npala fun awọn onimoto wipe ọna ti motọ ni lati gba ni ha, eyi ko tọ rara, o tọ o si yẹ ki omo enia sa asala fun ẹmi rẹ, a fẹ ki a ṣe akiyesi pataki lati odo awon enia to nwa lati oko, ti nwon ba ti gbo fere moto nwon ma salo fun bi buso (mile) kan titi moto yio fi koja tan ṣugbon amoju nyọ awa oinowe lẹnu pupoju oun lori dabi ẹni pe onmu iya tabi iku ojiji ba wa lode oni

SI AWON AWA MỌTO

A ko le koja lai ko ba ẹnyin awa moto soro ṣoki, nitoripe ẹmi awa ẹda ko pe meji, Oluwa ninu anu rẹ yio si ma ṣo olukuluku wa, pupo ninu awa moto ni ko ni suru to rara igba melo ni a ti gbo wipe oyinbo kan wa moto o lo fi pa enia? ako so wipe ko si ṣugbon ko pa to bi ti awa omo onilẹ ti a mo ayinnike ilẹ wa eo ri pe o yẹ ki a kiyesi ara wa gidigidi, bẹ ki ṣe wipe a ka mo moto yi wa ṣugbon amoju lo nyo wa lẹnu. Nitorina a bẹ ẹnyin awa moto wipe ki ẹ ma ni suru, ki esi ma fi lakaye ati ogbon wa moto nyin nigbakugba ti ẹ ba nṣe eyi iku moto yio ṣe owon fun wa.

Bakanna ni awa ti a nfi ẹṣẹ wa rin a dabi ẹni wipe nigbamiran a ma ka iku si oun kekere nipa wipe ti jamba ba nbo lẹhin wa a o ma so pe se bi nko si lona moto kini mot yio wa ṣe lodo mi. igbakugba ti a ba ti gbo fere moto lẹhin wa o fẹ duro ni tabi ko fẹ duro ẹ jẹ ki a sa asala fun ẹmi wa nitori ti ẹmi kanṣoṣo ba bo o di gbere o tun di arinna ko o tun di oju ala o tun di ojo ajinde.

Lakotan ẹnyin okawe wa e maṣe jẹki a fi ilaju ti ko tọ ba igbesi aiye wa jẹ, nigbati irufẹ ilaju yi ko ti de moto tabi orisirisi iku ojiji go si ṣugbon lati igbati ilaju ti bẹrẹ ni a ti nku iku airotelẹ, a kole ri ojo kan ti moto ko ni ṣẹ enia lẹṣẹ tabi kopa, Oluwa ninu anu rẹ yio ma ṣo wa ṣugbon ko si igbati Oluwa ki ṣo wa, o wa ku si owo awa papa lati sora wa gidigidi, ki oni kẹkẹ maṣe fi oju di onimoto, ki ẹlẹṣẹ mose fi oju di onikẹkẹ ti a ba le le ṣe eyi dajudaju oni moto pa enia kan ola pa meji bi adiẹ ko ni si mo.

DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

**MODUPE PRINTING PRESS**

16, Bamgbose Street, Lagos. Phone 21985

# Iwe Si Ọlọtu

## Imoran Si Awon Ilu Ijomu

Olotu, mofẹ ki ẹgbami faye lati fi ẹdun ọkan mi han fun awọn Ilu Ijomu. Ọmọ Ijomu ni emi na ti mo fẹ ba wọn sọrọ yi. Ohun ti mo fẹ bawọn sọ na nipọn pupọ ogba ọgbọn papa fun awọn agbagba Ilu Ijomu toripe ejo loyẹ ki afi sabẹ owule sun, koṣẹṣe lati fi ina sabẹ owule sun rara. ọrọ kansẹlẹ ninu ilu Ijomu laipẹ yi ọrọ na buni pupọ. o jẹ eyiti ọkan tomọde tagba baje si, sugbọn awọn agba ilu koni itara si ọrọ na rara.

Osi ndun awọn ọdọ ilu yi di isisiyi sugbọn bi oti ndun wọn to yi, wọn koni enu ọrọ niwaju awọn agbalagba. Awọn baba wa na lo ma npa lowe wipe agba ki wa lọja ki ori ọmọ titun owọ, toto osẹ bi owe.

Ti awọn agbagba ilu kobani se afojudọge amoran sika, oyẹ ki wọn le ni ipinu to dara lori ọrọ na toripe ọrọ Ọlọrun sọwipe ẹnikẹni ti o ba fi ida pa enia, ọwọ ida ni ohun na yio ti subu Ti wọn sikọ lai seto atata lori ọrọ na, o yẹ ki wọn mọ daju pe odu ni oye, bopẹ yio yi kan ẹnikọkan awọn na, sugbọn mobẹju, monsọrọ yi pelu owe nitoripe emi kofẹ la ọrọ ra mọlẹ rara, ṣugbọn ti ẹ bakọ laiseto, ọrọ ikọkọ nigbangbo ma lonbọ o. Nidi eleyi mo bẹ awọn agbagba wa, kiwọn lọ wa ara wọnjọ lati seto, kiwọn masẹ bẹru ati sọ otitọ, toripe ẹhin olododo ni Ọlọrun wa, asotitọ kosi ni ku sipo ika rara o.

Ọlọrun yio tun ilu Ijomu se dada o, nisisiyi, ati dagba ninu ẹkọ iwe ati imọ esin gẹgẹ bi onigbagbọ ati imọle, koyẹ ki aje alaisotitọ rara, tobajẹ ilu miran bi Oro, Iludun tabi bebẹ ni iru ọrọ yi ti sẹlẹ awọn wọnyi yio ti sẹtọ fun iru enia bayi o.

Nipari ọrọ mi si yin, mofẹ ki ẹmọ pe koyẹ latj fi ika sarin ilu o, abi ẹyin ilu sun ni? E wọ Ẹkogbọdọ sun rara.

Modupe lọwọ Olotu, Isu ọmọ yio jina fun ọ jẹ o.

Emi ni
Ọkunrin-meta
Ijomu-Ọtun-Oro.

### Mo Kin Olotu Lehin

Inu mi yio dun bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ bale gbami laye ninu iwe Irohin ti oṣẹṣẹ njade ṣugbọn ti o gbajumọ bi owo ni ilẹ enia dudu ati ni okere.

Ọrọ mi na ni wipe mokin ọrọ olotu ti osọ sinu iwe yi nipa ọmọ-gbigbe ninu iwe irohin yi ni ọṣẹ ti okoja lẹhin. Mofẹ gba ẹyin onkawe wa ti koba ka ọrọ olotu ti ọṣẹ ti okoja yi ni iyanju ki wọn o jọwọ lọre ka wo nitoripe kosi eniti yio ka ọro na wo ti koni fi ara mọ ọrọ olotu na. Nitorina abẹ awọn Ijọba Nigeria ki wọn jọwọ kiwọn bani mojuto ọrọ awọn ajọmọgbe yi

Ati wipe ki Ijọba ki ojọwọ ki nwọn o ma tete ya si gbogbo ọrọ ti awọn enia ba ti nsọ si inu iwe Irohin.

Eṣe pupọ Olotu, ọwọ yin yio ma roke amin, ọkọ ọba koni sa yin lẹsẹ o amin.

Bello Ọla. Gbadamọsi
I B A D A N

### Ela eyi yemi

Ejọwọ ẹgba mi laye iberẹ mi yi, Ejọwọ kini ogbe ara duro Inu logbe ara duro tabi Oju. Nkan to mu ki emi bere nipe emi gbawẹ ni ọjọkan, nigba toto dede ago-mẹta ọsan oju mi ko riran mọ, ara mi ko la gbara mọ.

Olotu modupẹ aye tẹgbami
Salawu Bọlaji,
Lagos.

Ejọwọ ẹgba mi laye lati bere ọrọ kan lọwọ awọn akẹkọ bibeli wa, Ejọwọ mo iẹ mọ inu Ijọ ti Jesu wa ni igba to wa ni aiye, ati pe Sọsi wo ni mọ lọ.

Isaa Ọlọrunbẹ
Lagos.

### ALỌ APAMỌ

1 Iyalode Ile Ifẹ, a ro igba aṣọ ma ba'lẹ. 2 Oriṣa kekere akunlẹ bọ. 3. Ọpa tirin kan'lẹ, o kan'run
4. Pẹbẹ r'Ọyọ, pẹbẹ bọ.
5. Ebu iṣu kan yi aiye ka.
6. Awẹ obi kan gadagba a jẹ r'Ọyọ, a jẹ bọ. 7. Ayaba pẹlẹngẹ le tiro si gengẹ oju.

ITUMO
Ere
Orun
Atẹlẹsẹ
Ọjọ
Ọlọta
Igi Ọpẹ

